# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFỌJUSEN:—

"Emi yio fi ohun t'o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi".—W. T. Stead.

Vol. I. No. 49. SATURDAY, JUNE 16, 1923. FOURPENCE.


ỌGBẸNI OYINBO F. A. PICKLES

nṣe *Cinema* ni Opopo nla lẹmẹta lọsẹ. Awọ-sẹju ni awọn aworan rẹ. Ina Manamana ti a si fi nṣe Ẹrọ na mọlẹ bi ọsangangan. Orẹ, lọ fi onjẹ oju f'oju nibẹ. Ẹmẹta lọsẹ lo nṣe e *Monday*, *Wednesday* ati *Saturday*, ni agogo mẹjọ abọ alẹ (*8.30 p.m.*)

**Arnold Schlesinger**

Ile owo Oyinbo German Hamburg.

Iwọ le rańṣẹ Ẹrọ-Iranṣọ "*Mundlos*" ati "*Adler*" nibẹ bẹ si fi Ẹrọ-rinran bata pẹlu.

Ẹ tọ Ọgbẹni A. Kessler lọ ni 7 Labinjọ kane, kọjọ Williams Street.

Mundlos on top Mundlos.




A nranṣẹ onisirisi ọja fun enia to tete nlọ nilẹ ni *Nigeria*.

Ọja tiwa ya. A si ni ọja wọnyi fun tita:—Ohun ero orin, Awo-Abọmalọ, Kẹkẹ-ologere t'Okunrin t'Obinrin, Waji.

Ẹ le ri Ẹrọ Iranṣọ "*Mundlos*" ra, lọdọ J. S. Johnson, Alhaji Masu, ati lọdọ H. Campos ti Campbell Street.

Mundlos on top Mundlos.


20 JUN 1923
20 JUN 1923

LAGOS STEVEDORING COMPANY

ALL STEVEDORING WORK
undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.
GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.
Estimates given for the handling of goods under any circumstances.
*PRICES ON APPLICATION*
to
**S. I. M. Johnson,**
2, Scale Square,
Phone 227 Lagos.
P.O. Box 198

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Oja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Oja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni ọnarun awọn ohun kikọle [illegible] tita ni owo ọpọku-ọpọku.

O ti nsowo Irin Isẹ locisunsi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onisowo Irin Isẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ o.

---

## ỌGBẸNI DURO THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, ita Faji, l'Eko, ni orisirisi Ọja to de [illegible] lati Ilu Germany fun tita; awọn nkan Awo abọmalọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ oja miran.

E lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni

Bi ẹ ba fẹ, e kowe si i. *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA

Ọgbẹni D. B. OSUNTOLU, onisowo Olatewaju ni ọpọlọpọ oja fun tita ni Ṣabo rẹ ni
No. 44. Balogun Street, l'Eko.
Nanu awọn oja rẹ ni iwọnyi:– Iboko tabi, Carpets
Panu Ikole, Aṣọ oniruru, Ileko, Baranje,
Olowonyo, Yomini (*Sallen*)
Ati orisirisi nkan alaiu miran, Ọja Ọgbẹni yi roju o si lere mau, ọpọlọ-ọpọlọ ni.
E lọ ra ti nyin nibẹ.

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AṢỌ NYIN FAYA, E LỌRAN.
AṢỌ NYIN FAYA, E LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati
MASINI-A-NJUWON
Ọgbẹni DURO THOMAS.
Onisowo-towolaw', ni awọn IBUSUN mẹrẹmẹrẹ onidẹ to ṣese de fun ti pẹlu awọn MASINI iranṣọ ti a npe ni *Gritzner* ti on ọlowọ ati ti ẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mase leti ita Faji, l'Eko.
Ifa nibẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ; owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.
E lọ ba Awure nyin pade nibẹ.

*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

——:o:——

### Ẹ KU, AJAGUNMOLU.

A gbọ pe awọn Ọgbẹni Withnell Majarọ Williams (Kuli Poy), ati Charles Ọbafẹmi ti nwọn ti lọ kọ iṣẹ *Lawyer* ni Ilu Ọba ti m'oribọ ninu iṣẹ na, ati pe laipẹ a o ka wọn kun awọn "Asọboto" larin wa nibi.

### SẸKITẸRI "IGBAKEJI" ỌBA.

Ọgbẹni . . A. Adenẹyẹ Titcombe Sẹkitẹri Aṣiri Alake de ni *Monday* ọsẹ yi o si ti pada lọ si Abẹokuta ni ọjọ diẹ sẹhin.

### ILE OLONJẸ LA ND' ẸBITI AIYA SI !!!

Mammy kan ti o jẹ *member Church Wesley* nibi lọ si *Class* rẹ ni *Monday* ọsẹ ...T, ṣugbọn ẹnu ya a pe titi o fi kuro ni ile *Leader* rẹ nibiti nwọn nṣe *Class* na, ọkankan ninu awọn *member* to ku ko yọ'ju, nigbati Mammy na si wa fi imu finlẹ lati mọ eredi rẹ o wa mọ pe Ọgọrọ Iyawo gbigbe to kun ita nisinsinyi ati Oku sisin ni ko jẹ ki awọn "Ara bi" wa:

A fi tirẹ silẹ gbọ ti ẹni ẹlẹni, ọ ganjọ la nsinku rẹ.!!!

### ALUFA IJỌ ST. PETER NṢE OHUN ARA.

A ba Ẹni Ọwọ J. A. Cole, Alufa Ijọ *Church St. Peter* yọ fun Isin alẹ to ṣẹṣẹ da silẹ ninu *Church* rẹ ni ede Gẹsi, ni ọsẹ.

### KI LẸ NṢE T' Ẹ PỌ TO YI?
### IYAWO LA MGBE O.

...gbẹni Edwin Ṣobo Ọṣin, Akọwe ni Ile ... H. B. W. Russell ti Ilẹ yi gbe ...dan Beatrice Adedoyin John ọkan ... awọn ọmọ Ọlọtọ ni 'yawo ni *Church* ...ya ni *Thursday* ọsẹ yi: owo a funa o.

### ỌKỌ 'YAWO GI 'ME TIKITI O.
### FOR GO WINNEBAH.

Ọgbẹni G. B. Pearse Akọwe ni Ile Oyinbo Awọn Ọlọkọ (*Elder Dempster & Co., Ltd.*) ti Ilẹ yi ati ọkan ninu awọn Iriju Pataki ti Ijọ *Brotherhood* gbe omidan Eyiyẹmi Abraham, ọmọ Ọgbẹni wa I. E. Abraham ni 'yawo ni *Kotu kekere* Ita Tinubu, ni agogo mejila ọsan yi. Iyawo a we Gele Arẹmọ o.

### ỌNA ỌFUN ỌNA ỌRUN.

Ọkan ninu awọn Oṣiṣẹ ni *Post Office* titun ti a nkọ ni Tinubu Street, ti a npe ni Jimọ re bọ silẹ lati Orule ile na niwọn agogo mẹ'a ọsan *Tuesday*, o si f'ara ... ọgan, a si gbe e lọ si ile Alarun.

Ọna Ọfun jẹ Ọna Ọrun, ni Gasikiya.

### EWU LỌ, LORI RẸ EWU LỌ, YE!...

Ori lo yọ ọkọnrin kan ni Kotu Ebute Meta ni ọsẹ to kọja, ti aya rẹ purọ mọ pe o fun on ni ogun ati ṣẹ oyun ti on ni fun u, nigbati a si pe Dr. Ṣapara pe ki o ye ogun na wo, o ri pe ki'ṣe ogun ṣiṣẹ oyun rara, o sọ pe nkan bi Ẹja Arọ ati ohun mimu oyun duro miran ni a fi ṣe egbog... na. Adajọ si da ọkọnrin na silẹ ko ma lọ; ọpẹlọpẹ Dr Oguntọla Ṣapara lara ọkọnrin yi, bi bẹkọ iba ma jẹ ẹnu ṣamu-ṣamu lọgba ẹwọn nisinsinyi. Lọwọ gbogbo obinrin aladunrunmọ, *Oluwa rere gba wa.*

---

### ADDITIONAL NAME.

I, Aina Johnson of 86, Ọdunfa St... or General Post Office Lagos, beg to ... Ọjọmu to my name and to be hencefor... known and addressed Aina Johnson Ọj...

## IRIN-AJO LATI EKO LỌ SI KAMERUN.

(LATI ỌWỌ AJEJI)

V.

Ibi iṣẹ ẹrọ ti o nṣe yinyin (*Ice*) omi Limbe ni o nyi ẹrọ na, ko si pe a ṣẹṣẹ nda ina si lẹ o to ma ṣiṣẹ, ori Limbe yi jẹ eyiti o nṣan si Okun, nwọn wa ṣe ẹsẹ kẹkẹ kan ti nwọn fi ọrọ so mọ ẹrọ ti o nṣe yinyin, ẹsẹ yi wa ninu omi, nwọn wa kọ ile yi da, nwọn wa se oju agbara si, ti o ba ya ti nwọn fẹ ṣiṣẹ, nwọn a ṣi oju agbara, omi a ma ṣan kọja yio si ma yi ẹsẹ kẹkẹ yi, ẹrọ a gbija ninu ile rẹ, iṣẹ yinyin ṣiṣẹ bẹrẹ niyẹn, omi Limbe yi jẹ omi Ol'okuta, ya ya lo si nṣan.

*Botanical Garden* wọn tobi pupọ, oniruru ohun ọgbin lo si kun inu rẹ, oniruru igi eleso ati Olorun-didun pọ pẹlu, nwọn ṣe ọna nlanla si arin rẹ, ibẹ dun lati lọ gbatẹgun nitori orun ki ipa ni ninu rẹ.

Ilu kan kekere ko jina pupọ si Victoria, Bota ni oruko rẹ, nibẹ ni oniruru ẹrọ wa lati ma fi gbẹ Cocoa, Bota yi si ni alabojuto ohun ọgbin wa (*Supervisor of Plantations*) nibẹ, si ni nwọn fi ṣe ibujoko Ọkọ ilẹ. Ọkọ ilẹ ti o wa ni Victoria, dabi eyi ti o ti wa larin Eko ri, o kere pupọ, o dabi ere ọmọde l' ẹgbẹ ti Iddo. Nwọn tun ni oriṣi Reluwe, eyiti nwọn npe ni *Monorail*, Enia mẹrin lo gba, nwọn a joko kẹhin s' ara wọn ni, meji, meji, agbara *Motor* lo fi nrin.

Ilu ti a npe ni Buea, on lo jẹ Olu ilu fun Victoria ati gbogbo Camerun ti o wa labẹ Ijọba Gẹsi, Buea yi jẹ agbara oke, o sin jin to *mile* mẹrindi-logun wakati marun ni rinrin rẹ, o ṣoro pupo nitori oke ni, enia yio ma gun oke ni titi yio fi de ibẹ. Ohun Ọgbin si pọ lọna ibẹ pupọ, awọn nkan bi igi Rubber, Cocoa, Ọgẹdẹ omini ati agbagba, janrẹrẹ ni, ko ṣe ṣe, o papọju Buea mu otutu pupọ o bi yinyin bẹ lo tutu niyẹn, ohun ọsin ati nkan ọgbin ilu oyinbo si yara dagba nibẹ.

Awọn Ẹlẹdẹ ilu oyinbo ti o wa nibẹ, titobi wọn ko ṣẹ ni wọn to ọmọ malu; bẹ si ni awọn malu ti ilu oyinbo ti nwọn wa nibẹ.

Nwọn nfun (*milk*) wara nibẹ ta lọna ti oyinbo nwọn si nṣe *Butter* pẹlu.

Awọn ẹfọ ilu oyinbo (*Cabbages Leek*) at oniruru nkan nbẹ nibẹ. Potato, ẹwa, Idunkun.

*Milk* ati *Butter* ṣa ni nwọn ko nta fun enia dudu, ṣugbọn gbogbo nkan ti o ku gba ni enia le ra ti o ba fẹ, mo ro wipe nitori Malu ko pọ ni. Omi ilu yi tutu pupọ l'arọ kutukutu enia ko le tọwọ bọ ọ; Bo ti wu ki omi ho to, bi a ba gbe silẹ, ki o to to iṣẹju marun, yio tutu ṣa ni.

Ile nlanla pọ ni Buea ju Victoria lọ, nitori Buea ni Jamani papa fi ṣe Olu, Ile Gomina wọn nibẹ papin ni, ọna opopo si fẹ dada; ibi ti awọn ara ilu papa wa to abọ wakati si ti oyinbo, larin iyanfi ati palapala okuta ni. Eyiti awọn ara ilu mi'an wa iyẹn ṣe pẹtẹlẹ diẹ, awọn Gambari sin pọ ni ilu yi pẹlu.

Ni ilu kan ti a npe ni Soppo, ni *Station* Reluwe, ko de Buea, Soppo yi kọ ju ogun iṣẹju si Buea; Ile awọn ọmọ ogun Jamani kan wa lọna ki a to de Soppo yi, jankan jankan lo to; Ibẹ si ni awọn Onisin Padi wa nisisiyi; (*Roman Catholic Mission House.*)

Isin Ọlorun lọna igbagbọ wa nibiu pẹlu, Ijọ ti Aguda; Baptist ati Basel. Ọgbẹni Hutchinson ati Olurẹmi Johnson awọn lo nṣe akatakiti ti isin lọna ti Anglican ninu ile isin ti Basel. Ni ijọ Ajinde ni nwọn pin ẹbun fun awọn ọmọ ile ẹko ọjọ isinmi ti Buea *Station Church*; Nwọn bẹrẹ isin ni agogo Ọgbẹni Johnson ati Hutchinson si ngba ni ra titi nwọn fi kọ orin keji Lẹhin orin keji, ni nwọn wa bẹrẹ lati ṣe ohun ti o mu wọn pejọ, eyini ni lati pin ẹbun fun awọn ti o ṣe dara. Ọgbẹni Olurẹmi Johnson joko sori aga, awọn ogbẹni meji ti o ti Victoria wa sin wa lọtun ati osin rẹ, Ọgbẹni J. O. Thomas ati I. B. A. Robinson.

Awọn ara ilu wọnyi le korin pupọ, Jamani kọ wọn niyẹn tase, bi o tilẹ ti jẹ pe ko si duru, ko si ikankan ninu gbogbo orin ti nwọn kọ ti o tase, yungba lo ndun.

Ilu Tiko jẹ irin wakati mẹfa si Victoria, mẹfa si ni si Buea pẹlu. O wa leti omi, Ọsa rẹ jin pupọ, Ọkọ nla elefin le de si ara kereni rẹ, i si jẹ ebute fun awọn ti o ba fẹ lọ si D ti nwọn ko ba fẹ gba ori okun ti Victoria; Ọsọ ni Ọkọ igbaja (*Steam Launch*) nti Doala wa si Tiko fun Ọja ti nwọn nna nibẹ. Ohun Ọgbin si pọ lọna lati Victoria de ilu yi; Ọgẹdẹ Ọmini ti o jẹ pe igi rẹ ko gun ju ẹsẹ mẹta lọ, ti nwọn ba so tan, ọmọ wọn a f'ẹnu kan ilẹ ni, o lọ sua, Oko awọn Jamani ra dun lati wo, o dara pupọ, o si mọ fefe. Gbogbo Oko wọnyi, ọwọ awọn Gẹsi lo wa nisisiyi, ti nwọn si nfi wọn ṣe'fa jẹ lakoko.

Awọn Yoruba wa diẹ ninu gbogbo ilu nwọnyi, ti nwọn wa nṣe owo, papa awọn Imale, awọn pataki ninu awọn oniṣowo Victoria ni wọnyi:—Alufa Kuranga, (Olori gbogbo Yoruba) Emilia Lande, Alice Oshodi, Mọriamọ Ẹlẹwade, Tairu Agbe, Sadatu Ajokẹ, Awanatu Adebiṣọla Ajokẹ, Rufai Kekereogun. Ni Tiko Noah Ipayẹ (Olori gbogbo Yoruba) Abudu Baruwa, Mọyamọ Ledijo Patience Williams, Christiana Williams. Bi Buea ti jẹ agbara Oke, ko si awọn oniṣowo tara nibẹ.

Iwọnyi ni awọn nkan ti o ta diẹ nihin:—A pipa Ọlọpa mẹrin; Printi ti owo rẹ ko po aworan eyiti awọn (*Syrians*) Kọraa nta, Ta Iṣana (*Matches*) Gari, Aṣọ Kaki, *Shirt* Awọtẹ Padlocks, Hasps ati Staples. Iwe ati apo

(*Writing Papers and Envelopes*) ẹja oniyọ (*Salt-fish*) ati awọn nkan wẹwẹwẹ miran ti owo rẹ ba rọju.

Ẹniti yio ba wa na'ja nihin yio san owo ori ṣile mẹjọ lodun (8/-) owo ibusọ ṣile mẹta loṣu (*Market dues 3/- monthly*) owo ati ta ọja pọun kan l'ọdun

Ọpọlọpọ awọn oniṣowo Yoruba lo nti Duala sa wa si ibi nisisiyi nitori owo yiyi padà; eyi si nmu ọpọlọpọ igbese wa, owo Dollar Faranse ti o ti jẹ marun rẹ ni Pọun kan ti Gẹsi, o ti di mejila nisisiyi, *Franc* rẹ ti o ti jẹ nkan bi mẹdọgbọn fun Pọun kan ti di mejileladọrin.

*Koi ti pari*

---

## LAW AND POLICE.

*By Awodi-oke.*

---

REX *versus* EMANUEL OTITỌJU.

The accused aged about 21 pleaded guilty to theft of Gas Lamp value £10 from Tinubu Church during the month of May, 1923.

The facts of the case are briefly :—

The Sexton of Tinubu Church opened the windows and doors of the Church for divine worship as usual in the month of May—He discovered after the end of the evening service that the Gas Lamp hanging in the middle of the Church had been removed. He complained to the Authorities of the Church, and the lamp was traced up to an Auctioneer's Mart, where it was taken to by the accused. The Court passed sentence of three months on the accused.

REX *versus* BELO ADEOSI & JUBRILLA.

For stealing Jewellery value £14. 10. from a Cripple.

The accused Belo Adeosi pleaded guilty, and was sentenced to six months imprisonment, after admitting previous conviction of three months for theft at the Lagos Police Court.

The facts are shortly :—

The accused was allowed to take shelter (in a rainy day) in the house of the Complainant who is a Cripple. The Jewellery was left lying on the window close to where the accused was sitting. The complainant discovered after the accused had gone that his jewellery was not where he had left it. He subsequently reported to the Police and the accused Belo Adeosi's house was searched, and Jewellery found.

The Court passed sentence of six months on the accused and discharged the accused Jubrilla.

REX *versus* JAMES

For using Juju in his Master's food the accused, a lad of about 19 was convicted before His Worship Mr, H. S Barkeley at the Lagos Police Court.

The facts are shortly :—

The accused whose duty it was to carry meals from the Grand Hotel to his master's Quarter's daily, was called upon for explanation by his master for the strange taste in the Bovril, stuffed Onions, boiled Ham, and Potatoes served by him.

He had no explanation to give, and a medical Officer was called in—on examination the food was found to contain a substance probably, a native love potion which is supposed to produce stray affection between the giver the recipient.

The Court passed sentence of three months on the accused.

---

## ASỌYE T'O BẸ ṢUỌ.

### Mo gbadun Alasọye *Professor* Deniga ni Breadfruit School, Lagos; ni alẹ Tuesday, MAY 22, 1923.

Ọrẹ mi atijọ, ẽṣe t'õ wa o?
À b' o nba wa jà ni?

O ya ni lẹnu nigbati Prof. Deniga fi ara ti ibi wẹrẹjẹ kan ni Breadfruit School, ti o nsọ itan awọn agbalagba Eko mẹrin fun wa ni ede wa, ki a le ranti rere ti nwọn ti ṣe silẹ fun wa, ati pe ki awa na le wa ọna ti awa yio fi ẹsẹ le ẹsẹ wọn ki a to pẹhinda.

O sọ itan nipa ti Dr. Johnson, Bishop Crowther, Ijoye Taiwo Olowo ati Ọlọla Otonba Payne. Ẹkọ pupọ l'a si ri kọ nipa igbe-aiye awọn ẹni nla mẹrin yi.

O sọ fun wa pe Dr. Johnson lo ṣe Iwe-itan ilẹ Yoruba, eyiti ko le jẹ ki a gbagbe irandiran wa lailai, on ati ẹgbọn rẹ Rev. S. Johnson ti Ọyọ. Iwe yi gba wọn to ogun ọdun ki nwọn to pari rẹ. Nwọn si nta iwe na ni £1 1s. 0d. loni, ni Bookshop l'Eko. Bishop Crowther lo yi A B Ç si A B D ni ede Yoruba, o ṣe Bibeli ni ede wa pẹlu eyiti o jẹ ki Isin igbagbọ tete ye awa enia dudu, ẹ ko ha ri ore nla to ṣe fun wa bi? Otonba Payne lo sọ gbogbo awọn adugbo Eko ni orukọ bi Tokunbọ, Oluṣi, Sabado, Oke 'tẹ, Ọbadina, Tinubu ati ọpọlọpọ miran pẹlu, o si tun ṣe Iwe-itan Eko. Ṣugbọn ẹ ṣakiyesi pe nmu gbogbo adugbo wonyi, ko si eyiti a pe mọ orukọ Ogbẹni na rara. Eyi fihan wa pe ko mọ ti ara rẹ nikan. O fihan wa

pe apęrę ni Taiwo Olowo hun ta lakoko bęrę iṣę rę, ṣugbọn nigbati o di igba dię si i, o di Oniṣowo nla, o si di kori-kosun "Ọba Goloba," o di ọkan ninu awon Alaṣę ilu. N torina iṣę ti a ba nṣe, ki a fi ori ti i. Oluwa Alaraṇṣe yio ranti wa si rere. Ṣugbọn ju gbogbo rę lọ, o tọ ki awa odọmode ma lọ si irufę ipade bayi, fun ẹkọ pataki ti a le ri kọ ninu rę.

ĘKI-MOGUN

---

# EKO AKETE.

EKO, SATURDAY, JUNE 16, 1923.

---

## Ę KILỌ F' ARIJĘ NPJA KO JĘ A SINMI.

Ni akoko ọdun kekere awọn Imale to kọja, a ba gbogbo Musulumi ilę yi yọ, fun ija wọn ti a gbọ pe o pari, gbogbo Iwe-Irohin ọsọ̀ọ̀ ti ilu yi lo si ba wọn yọ pęlu tobę ti ęnikęni le fi wipe aiya ilu kole ṣai balę nisinsinyi. Ṣugbọn kini a tun ngbọ lati ęnu ọjọ dię sęhin? ohun ti a tun ngbọ nipe awọn kan ti nwọn dagba ti wọn ko da'nu—Adię funfun ko mọ'ra rę lagba—nti Lemọmu Braimọh pọnpọn ki o ma ṣe gba ohun ti a sọpe nwọn ti fi ori rę ti sibi kan ni jọsi nigbati nwọn lọ si 'le Ọba fun rogbodiyan ọrọ na, ni akoko Adele Ọba Alexander George Boyle, ti o di Sir Alexander Boyle, nisinsinyi: a ko mọ eredi rę ti irufę awọn enia wọnyi fi nri ija yọ; irufę awọn enia wọnyi ni o yę ti o si tọ ki Ijọba wadi, larin awọn Imale ki a si ṣe ohun ti o tọ fun nwọn, nitori alafia Ilu yi ko dun mọ wọn ninu.

Nigbati a bę ọrọ yi wo, a sọ fun ni pe awọn ti o nti Lemọmu na pe ki o ma gbọ sisun ki o ma gbọ sisè mọ ni ti ọrọ na ko ju męta lọ. (A mọ oruko wọn;) a ro pe Lemọmu yio f'oju agba yę ọrọ yi wo, kò si ni ję ki awọn ọmọ ina yi ti ọwọ on bọ ęọ̀lọ̀ mọ. Awodi oke ni awọn ọmọ bilisi na, ti nwọn koimọ pe ara ilę nri wọn.

Ęnyin ara Ilu, nisinsinyi ti a npe ni ki a wa lọwọ, ninu Iṣę-Ijọba irufę anfani ti ko ti si ri lati igbati Eko ti mọ ara rę ni Ilu ti o wa labę Abõ Ọba King, o ha yę ki a gbọ wipe a tun nṣe ere kọ̀'ọ̀kọ́lọ́ nipa jija si ohun ti ko to tun bi? ębę ni a mbę Oṣika ki o ba ni tun ilu rę ṣe, nitorina a bę irufę awọn enia wọnyi (Nwọn mọ ara wọn) ki nwọn ma ję ki ọrọ awọn ayọ ṣuti si wa, pe a ko le papọ ṣe ohun rere kan, ṣę si wa lara nipa pe ki a tun wu ọrọ atijọnijọ sodi lati fi di iṣę ribiribi yi lọwọ.

Lemọmu Braimah, "Eko Akete" ke s ọ bi Olori awọn Musulumi ni Eko, ki jęwọ ipo ti Olodumare fi ọ si, ki o ma s ję ki ęnikęni ninu awọn ọmọ ęhin rę t'ọwọ rę bọ ina, tabi ki o fi ọ "di Elekuru" ọrọ pala-nta.

B'o ba baję iwọ!
B'o ba baję iwọ!!
Ọlọrun ma ję ko baję.

---

SHORT STUDIES ON YORUBA WARRIORS.

By the EDITOR. II.

[Copyright]

## OGEDE-NGBE GBOGUN-GBÓRÒ.

Chief Ogede-ngbe was born in a farm in Ileṣa on or about 1834; his "bringing out ceremony" on the 9th day was performed by the Ọwa of Ileṣa, in accordance with the Ifa Oracle consulted by the child's parents, when it was in the womb; and the oracle went on to predict the future brilliant career of the new-born babe; a cow was slaughtered in honour of the festive day; on Ogede-ngbe arriving at the age of discretion, it was not very long, before he began to show his countrymen the stuff—military—of which he was made. In one of his expenditions he was made a prisoner, and brought to Ibadan, during the time Ogunmọla here it was suggested that he should be sacrificed to the god Ogun; his hands were at once tide backwise, and his mouth gagged; but through the good graces of Ogunmola, his life was spared and another human victim was provided for the sacrifice; eventually, he was liberated and allowed to return to his country, on reaching home, he was at once made the leader, or captain of the war-party during the Ọdọle war; he waged war with Ibadan for 3 years without break; after this, he went to Ipętu; here all his army repaired to him leaving their wives, children, etc., after they have been defeated by the Ibadans in the Ọdọle war; he conquered Isęyin in a 3 years' engagement; he got back all the Ijęṣas formerly taken

prisoners by the belligerents and went on an expedition against Ekun, Afo, etc., and conquered them; he was called back home, when the Ọyọs were waging war with the Ibadans in which fight, he was engaged for 18 years. It was shortly after this, that it is said, Governor Carter went to the hinterland to settle the long standing feud existing between the different Yoruba countries. After peace was restored, Ogede-ngbe's guns and ammunitions were taken possession of, and brought down the coast by the British Government. On one occassion when he was asked why he did not like being crowned he replied that as no royal blood was flowing in his veins, such step if undertaken by him, will amount to nothing, but sheer folly and fraud; during his military exploits, we are told that Labinjọ, a contemporary of the late Chief Daniel Conrad Taiwo's *alias* Taiwo Olowo, was his principal "Secretary of State for War" as he it was, to whom orders for guns and ammunitions from Europe were generally entrusted, by the veteran chief. Chief Ogede-ngbe waged war with the different tribes of Yorubaland in war with his country, for several years. In stature, he was finely built; being short, plump and nimble; he was a veritable terror to the enemies of his native land; he departed this life at Ileṣa in 1906.

## THE BIRTH OF A NEW ERA.

By THE EDITOR.

A Public meeting in connexion with the proposed founding of THE NIGERIAN NATIONAL DEMOCRATIC PARTY was held at The Glover Memorial Hall on Thursday last at 3 p.m. under the auspices of the *Ilu* Committee.

Counsellor J. Egerton Shyngle, Barrister-at-law, Chairman of the *Ilu* Committee presided, supported on the *dais* by the *elite* of the Community.

Amongst those that addressed the meeting, besides the Chairman, on the Aims and Objects of the proposed Party, strictly political, with *particular reference to the impending Legislative Council Election*, are Messrs Thomas H. Jackson, J. Bagan Benjamin, Prince Ọṣọlake Davies, Ex-counsellor Adebẹṣin Fọlarin, Adeyẹmọ Alakija, Herbert Macaulay, A. Bank Anthony, L. A. Cardoso, Sanni Shitta Seriki Musulumi, Abibu Oki Balogun, Braimah Igbo, Chief Oluwa, Chief Eletu-odibo, Kasumu Ayọrinde.

The hall was *crowded to overflowing*, and before the dispersal, at 7 p.m., *a Mandate was received from the people* unanimously authorising the birth

of the party and pledging their financial and moral support.

Ring out the old, ring in the New,
Ring out the false, ring in the True.
Ring out the SELF, ring in the SERVICE,
RING IN THE COUNCIL THAT IS TO BE.

[*With Apologies to Tennyson.*]

---


## C.M.S. GRAMMAR SCHOOL,
LAGOS.

The Committee of the "Old Grammarian Sports Section" heartily thank those Gentlemen who have assisted them by giving Financial or personal help.

GEO. I. PHILLIPS,
(*Hon. Secretary Sports Section.*)

---

## A DUPẸ ỌJỌ.

Ọgbẹni Emanuel Adekunle ti 58, Campbell Street, ṣọpẹ lọwọ gbogbo awọn Ọrẹ ati Ojulumọ to wa ba a daro nigbati Baba rẹ Moses Adekunle tẹ̀ri gba'ṣọ ni lọlọyi.

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.
LAGOS—EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Olivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African Association, John Holt, Miller Bros. Cooperative Wholesale Society Ltd., Jurgens Colonial Product.
£16—£16 10 fun *ton* kan

EPO.
£26 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.
£27—28 fun *ton* kan bakanna.

---

KANO—COMPETITIVE PRICES
Ground Nut—£14 10 per ton
Skins 1/9 per lb, Hides 5d per lb

*Telegraphic Address* :—**BANK ANTHONY**

TOKUNBO, LAGOS.

Telephone No. L230, G.P.O. Box No. 300.

*Residence and Office 137 Tokunbo Street Lagos.*

Ọgbẹni A. BANK ANTHONY AND SONS jẹ Onişowo to nranşẹ ọja fun tita lati ilu ọba (*England*) wa. O si ma nfi ọja şọwọ sibẹ na pẹlu.

Diẹ ninu ọja ti o ma nra ni ilẹ yi ti o si ma nranşẹ ni wọnyi :—

Gẹd r, Rubber, Cocoa, Ekurọ, Epo. Obi, Igi Osun, Agbado, Iwo Malu, Awọ orişirişi.

Diẹ ninu awọn ọja ti o ma nranşẹ fun lati Ilu Ọba (*England*) wa fun tita ni ilu wa ni wọnyi. Aşọ orişirişi, Akara Oyinbo, Ẹran oniyọ ati ọpọlọpọ nkan miran bi iru eyi ti o ta ni ilu wa ati Posi isinku iru eyi ti awọn oşişẹ wa ko le şe ni ilẹ wa.

Wo aworan ọkan yi, wa si ri daju pe awọn oşişẹ ilẹ wa ko le şe iru rẹ.



Irohin ko to afojuba lọ si ile rẹ ni No. 137 Tokunbọ Street wa si ri daju pe ki işe ti asọdun o ni ti talaka o si ni ti Olowo eyiti a fi igi şe tabi eyiti o jẹ onidẹ (Brass)

Ẹ kọwe tabi ki ẹ ja waya si i a o si fi Posi ranşẹ si nyin nibikibi ninu *Motor Transport.*

## All for Bicycles and Motors.

Ask for KADUNA STORE,
No. 81, Ọdunfa Street,
Near the Famous Building of
Mr. Andrew Thomas, Lagos.

*At reduced prices*

Special Dunlop Bicycles Tyres Beaded-edge 12/-
do. do. 15/-

The above Tyres are specially for Rudge-withworth and German Cycles and we have complete workshop for repairing of all kinds of machinery. .Send all your repairs' Bicycles, Motors, Sewing machines, Gramophone, painting, enamelling work soldering, etc., to the Properitor at the undermentioned address. All Bicycles spare parts on sale.

SAM. A. CLAY,
No. 1 Macauley Street,
or at Workshop, 81, Ọdunfa St.
Lagos.

*Telegram Address:*—KADUNA STORE,
81, Ọdunfa Street,
Lagos.


## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.


## The Philharmonic Band.



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ wọn, ko kọ iwe si
*THE SECRETARY.*
c/o Aafani Motors
The Marina Lagos.

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

MRS. FRANCES ADEYEMI THORPE (NEE GREEN) K'ogeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si Iṣẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ riran ni aṣa orişirişi ko ni ẹgbẹ.

Ẹyin ọmọge ti ọfẹ iṣẹ kọ, Ẹ lọ ri i.

## DRESS-MAKING.

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

## "O ṢE' WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ lọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

### ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

### ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | —St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | -St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev S. J. Gansallo |
| 9 a.m.... | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |

### WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. J. Allen Angus |
| 7 p.m. | do. | Rev. |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. E. K Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. S. A. Pearce |
| 7 p.m. | | Rev. E. E. Williams |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | do. |
| 7 p.m. | | Rev. S. A. Pearse |

### AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehuvah Shalom | Rev. Suptd. G. A. Oke |
| 7 p.m. | do. | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Erelu | Bro J. T. A. White |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. H. Lawson |
| 9 a.m. | Bethel | Bro. A. Aboyade Cole |
| 6 30 p.m. | | Rev. E. A. Akiọla |
| 9 a.m. | Zion | Bro. S. O. Ilọri |
| 6.30 p.m. | do. | Bro E O. Peters |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. W. K. Fatunwa |
| 4.30 p.m. | | Rev. N. J. D. Shomuji |

### FIRST BAPTIST CHURCH

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. J. O. John |
| 6 30 p.m. | | Rev. J. [illegible] Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Bro. J. J. Tubi |
| 4 p.m. | | Bro. Joseph Bandele |

### EBENEZER (BAPTIST)

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. S. M. Phillips |
| 6.30 p.m. | Bro. John Apena |

### BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Bro. Daniel Adesanya |
| 7 p.m. | | Prof. Adeoye Deniga |

### St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

### AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde

5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.)

### COLONIAL CHURCH (ODAN

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon ;
Rev. H. A. Lewis

### SALVATION ARMY.

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

### CHURCH OF GOD

10 a.m 22 Ọdunlami Street, Bread Breaking
7.30 p.m. Campbell Street Open Air Service
John P. A. Taylor & Wm. C. T. Terrell

---

MESSRS. J. R. THOMAS & SONS of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc. etc. to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori, Aro and Olokemeji Stations at very moderate prices This venture has already been opened by them to the public at the aforesaid Stations any one travelling up to Ibadan and back and needing supply of any kind of refresh ment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa.*

## ALASE LEATHER FACTORY
"ILE ALAWỌ"

Awọ ẹsẹ bata (*sole-leather*) ti a ṣe daradara, ti o lẹ ti o si pupa yọ, ati Awọ Hausa ni orisirisi awọ, yala ni pupa, funfun, dudu, elefe, ati orisi awọ miran ni a nta ni ọpọku ọyọkụ.




Bi o ba fẹ wa wo Ile Awọ-nla yi, ti iru rẹ ko si ni *Nigeria*, bi bẹkọ kọwe ẹọwọ pẹlu owosi:—

E. B. BEYIOKU-ALASE
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawobata, Eko.

## ỌRA BOOK SYNDICATE
33, Ọbun-Eko Street, Lagos.

Have just received consignments of :—

Writing Papers, Envelopes, Carbon Papers, Luggage Labels, (Assorted sizes & Colours,) Paper Fasteners, Paper Clips, Pen Nibs, Erasers, etc., etc., etc.

Give a trial and you will always like to have our service.

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkorin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD
8, Tinubu Square, Lagos.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigne?

Ọpọlọyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:—
8. TINUBU SQUARE, LAGOS.

## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYE
Fun Ile Eko.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. Alawọran | ... | 3d. |
| Iwe Alawọran Kini | ... | 7d. |
| Iwe Alawọran Keji | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sa kan nitori ogun Germani, ṣugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. nino ilu yi tabi lẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awọke inu wọn dara fun ọmọde to, pupọ ti o ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ọnti o ti jẹ oluko awọn ọmọde fun ọdun pupọ ti a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kose ise oore nlanla.

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lodọ onkowe ni ẹdun owe, 66, Ibadan Street, Ebute Meta.

Printed at "Tika-Tore" Printing Works, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Weekly and Gr...